# A TA JOSẸFU SI EGIPTI

## Gẹnẹsisi 37:1-36

## ẸKỌ 33 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ fẹ awọn ọtá nyin, ṣore fun awọn ti o korira nyin" (Luku 6:27).**

### Ọmọkunrin Naa ti a n Pè Ni Josẹfu

Josẹfu jẹ ọkan ninu awọn ti iwa wọn wu ni lori ju lọ ninu awọn akọsilẹ ti o wà ninu Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun. Ọpọlọpọ ori-iwe ninu Bibeli ni a ya sọtọ fun akọsilẹ itan igbesi-aye rẹ ati awọn ohun ti o ṣe, bẹẹ ni ẹni kan ninu awọn ti o kọ akọsilẹ nipa rẹ ko ri ohun kan ṣoṣo sọ lodi si iwa rẹ. Dafidi jẹ ẹni bi ti inu Ọlọrun, sibẹ ailera rẹ fara han niye igba; Mose, nipa adura agbayọri yí ohun ti Ọlọrun fẹ ṣe pada, sibẹ igba kan wa ti o ṣe ohun ti kò dun mọ Oluwa ninu. Ṣugbọn nipa ti Josẹfu a ko ri ohun miiran kà bi ko ṣe rere. O gbe igbesi-aye ailẹgan to bẹẹ ti ọba Egipti fi woye pe Ẹmi Ọlọrun wa ninu rẹ, o si wi pe, "Kò si ẹniti o ṣe amoye ati ọlọgbọ́n bi iwọ."

Gbogbo awọn arakunrin Josẹfu ni o dagba ju u lọ afi ẹni kan ṣoṣo, gbogbo wọn ni o si n ṣe itọju awọn agutan ati ọwọ-ẹran ni papa. Awọn arakunrin rẹ ki i ṣe ẹni rere bi Josẹfu, nigba miiran oun a si sọ fun baba rẹ nipa iwa buburu wọn. Ọlọrun kò fẹ ki awọn ọmọ rẹ jẹ "olofofo," ti yoo maa sure tọ awọn obi wọn lọ nigbakuugba lati fẹ ọrọ kekere ti kò nilaari di nla, ṣugbọn bi a ba ri iwa ẹṣẹ ni igbesi-aye arakunrin tabi arabinrin wa ti o tọ́ fun ibawi, iṣẹ wa si wọn ni lati sọ. Bi wọn ba lọ si ọrun-apaadi nitori a ṣe iranlọwọ fun wọn lati bo iwa buburu wọn mọlẹ, wọn le tọka si wa ni ọjọ idajọ ki wọn si wi pe, "Onigbagbọ́ ni iwọ i ṣe; ki ni ṣe ti iwọ kò kilọ fun wa?"

Ọmọde ti o ba n sun mọ Ọlọrun ni igbesi aye rẹ yoo maa ri iyọṣuti si nigba pupọ. Awọn ẹlomiran le maa pe e ni "enia mimọ́" tabi "alufa," tabi awọn orukọ miiran lati fi ẹ̀sìn rẹ ṣe yẹyẹ; ṣugbọn nigba ti wọn ba bọ sinu wahala wọn yoo tọ Onigbagbọ́ nì wa fun iranlọwọ. Wò o bi ijatilẹ naa yoo ti pọ to bi ẹni kan ti o pe ara rẹ ni Onigbagbọ ba kuna ninu irin rẹ pẹlu Ọlọrun!

### Awọn Àlá Josẹfu

Jakọbu fẹran Josẹfu ju awọn arakunrin Josẹfu iyoku nitori o jẹ ọmọ Rakẹli, ati nitori oun maa n gbiyanju lati ṣe ifẹ baba rẹ. Ootọ ni pe sisin ti awọn mejeeji n sin Ọlọrun mu ki wọn wa ni irẹpọ, bi irẹpọ ti maa n wa laaarin awọn Onigbagbọ tootọ lonii. Awọn arakunrin Josẹfu kun fun owu si i nitori oju-rere ti Jakọbu n fi han fun un; bẹẹ ni ọran naa tubọ wa buru si i nigba ti Josẹfu wi pe oun la àlá pe ìtí ti awọn arakunrin oun foribalẹ fun ìtí ti oun. Wọn tumọ àlá naa bi o ti tọ nigba ti wọn ro pe awọn yoo wa foribalẹ fun Josẹfu. Akoko naa si de ti wọn fi tayọ tayọ foribalẹ fun un.

Josẹfu tun la àlá ẹwẹ, ati ni akoko yii oorùn ati oṣupa fori balẹ fun irawọ ti rẹ̀; Jakọbu si beere bi oun pẹlu yoo tun fori balẹ fun ọmọ rẹ̀ kekere. O ba Josẹfu wi, nitori oun kò fẹ ki o gberaga ki o si gaba lori awọn arakunrin rẹ; o si fẹ ki o gbọran si awọn obi rẹ lẹnu. Ṣugbọn ala wọnyii jẹ iyalẹnu fun Jakọbu. O mọ pe ọmọ Ọlọrun ni Josẹfu i ṣe, ati pe boya Ọlọrun n fẹ fi ohun kan hàn nipasẹ ọmọ yii.

### Awọn Ikà Arakunrin

Jakọbu ni ọpọlọpọ agbo ẹran ati ọwọ́-ẹran, awọn ọmọkunrin rẹ ti wọn jẹ oluṣọ-agutan ni lati maa lọ lati ibi kan si ekeji fun pápá oko tuntun, eyi a si maa mu ki wọn jinna si ile nigba miran. Ṣekemu to bi iwọn aadọta tabi ọgọta mile si Hebroni, nitori naa Jakọbu n fẹ mọ̀ bi awọn ọmọkunrin yii ti n ṣe si, nitori naa o ni ki Josẹfu lọ bẹ wọn wo. Josẹfu ko jafara lati dá baba rẹ lohun, oun nikan si bẹrẹ irin-ajo ọna jinjin naa. Awọn ilu ti o wa ni oju ọna kò pọ̀, kò si si awọn akọle oju-ọna lati tọka ọna fun un ṣugbọn bi o ti n rin kiri ninu papa kan ni ẹba Ṣekemu, o ba ọkunrin kan pade ti o ti ri awọn ẹgbọn rẹ̀, ọkunrin yii si sọ fun Josẹfu pe wọn ti lọ si Dotani, bi mile mẹjọ siwaju si i. Josẹfu ni lati rin gbogbo ọna yii bẹẹ pẹlu, ṣugbọn nikẹyin, o ri awọn arakunrin rẹ̀. Njẹ inu wọn dun lati ri i ati lati gburo ile? Rara o. Ki o to de ọdọ wọn, wọn ti n ṣeto lati pa a. Wọn ranti awọn ala ti Josẹfu ti lá, bẹẹ ni inu n bi wọn sibẹ nitori ẹru ba wọn pe oun yoo jẹ alaṣẹ lori wọn. Wò o bi iba ti jẹ ohun iyanu fun wọn to bi o ba ṣe e ṣe fun wọn lati ri ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju ki wọn si ri Josẹfu ninu ọla nla ati ogo ninu agbara ni Egipti, gẹgẹ bi alakoso ti ọrọ rẹ jẹ ofin. Oun ni yoo jẹ oluwa gbogbo ilẹ afi eyi ti i ṣe ti awọn alufaa, oun ni yoo si jẹ oluwa gbogbo ohun-ọsin wọn. Nigba ti o ba n lọ ninu kẹkẹ ẹlẹṣin, awọn iranṣẹ yoo maa sare niwaju rẹ wọn o si maa wi pe, "Ẹ wólẹ̀." Ki i ṣe kiki awọn arakunrin rẹ ni yoo wolẹ fun un ṣugbọn gbogbo awọn ti o ba pade rẹ.

Ṣugbọn Josẹfu ni lati kọ jiya ki o to bọ sinu ogo rẹ. Ni ọpọlọpọ ọna ni igbesi-aye Josẹfu jọ ti Kristi. Jesu fi ara da irẹsilẹ ni aye, ati irora nla ni igba ikẹyin ọjọ aye Rẹ̀; ṣugbọn, wò o bi ogo ajinde Rẹ̀ ti to! Aṣẹgun lori iku, ọrun-apaadi ati isa-oku!

Josẹfu kò mọ aṣeyọri ti yoo jẹ ti oun ni ọjọ iwaju, boya o le maa jẹ ohun iyalẹnu fun un nigba miiran pe iru nnkan buburu bẹẹ ni lati maa ṣẹlẹ si i. Awọn arakunrin rẹ i bá ti pa a bi ko ṣe pe Reubẹni bẹbẹ fun un. Reubẹni

ni akọbi, oun ni yoo si dahun fun ẹmi Josẹfu niwaju baba rẹ. O damọran pe ki wọn ju u sinu iho ilẹ. Ero rẹ̀ ni lati yọ ọ jade nigba ti awọn arakunrin rẹ ba lọ ki o si rán an pada si ile.

Lẹyin ti a sọ Josẹfu sinu iho, awọn arakunrin rẹ joko lati jẹun. Ọkan wọn le to bẹẹ ti wọn kò tilẹ ni idalẹbi fun ẹ̀ṣẹ wọn. Ṣugbọn a o kọ ẹkọ niwaju pe wọn kò le gbagbe iwa buburu wọn yii, bẹẹ ni ẹri-ọkàn wọn da wọn laamu fun ọpọlọpọ ọdun lẹyin naa. Awọn eniyan le gbiyanju lati gbagbe ẹṣẹ wọn ṣugbọn Ọlọrun ko ni jẹ ki o ṣe e ṣe. Nigba ti ọmọde ba ṣe aigbọran si awọn obi rẹ ti inu rẹ ko si dun, Ọlọrun ni O n ba a sọrọ. O n fẹ ki o kaanu fun ẹṣẹ rẹ.

Bi awọn arakunrin rẹ ti n jẹun lọwọ, wọn ri awọn ara Iṣmaẹli ti n gun kẹtẹkẹtẹ wọn lọ si Egipti. Wọn jẹ oniṣowo, wọn maa n ra nnkan ni ilẹ kan wọn a si lọ ta a ni ilẹ miiran fun èrè. Wọn maa n ji eniyan gbé nigba miiran wọn a si ta wọn ni ẹru ki wọn baa le ni owo. Judah ro o pe ọna kan ṣi silẹ fun awọn arakunrin wọnyii lati ri owo nipa tita Josẹfu. Ọkan wọn le to bẹẹ ti wọn ko fi kaanu fun Josẹfu bi wọn ti n mu u lọ, ti ọkàn rẹ̀ bajẹ pupọ nitori wọn n mu un lọ si ilẹ ajeji, kuro lọdọ gbogbo awọn ti o fẹran, lati jẹ́ ẹrú.

Reubẹni ko si ni tosi nigba ti wọn n ṣe adehun lati ta Josẹfu, nigba ti o si pada wa si iho naa lati yọ Josẹfu jade, jinnijinni mu un lati ri i pe ko si nibẹ mọ́. Oun ni yoo si dahun fun ẹmi Josẹfu niwaju baba rẹ̀, o si di ẹrù nla fun un bi oun yoo ṣe doju kọ baba rẹ̀ lati sọ fun un pe ọmọ rẹ ọwọn kò si mọ́.

**Ẹ̀tàn**

Nitori ilẹ naa buru ati pe ọna naa jin pupọ ti Josẹfu ti la kọja, o rọrun fun awọn arakunrin wọnyii lati purọ fun baba wọn pe ẹranko buburu ni o pa a. Wọn tẹ́ aṣọ Josẹfu alarabara ti baba wọn mọ daradara bọ inu ẹjẹ ẹran kan ti wọn pa, wọn si mu un lọ fun un. Wọn kò wi pe a ti pa Josẹfu ṣugbọn wọn hu iwa irọ eyi ti o buru bakan naa. Awọn miiran ro pe bi awọn ko ba ti sọ ọrọ irọ wọn kò huwa buburu; ṣugbọn eniyan le huwa ẹtàn ki o si jẹbi niwaju Ọlọrun gẹgẹ bi igba ti o purọ gan an. Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọ Rẹ̀ jẹ oloootọ ati ẹni ti ọna rẹ gún ni ìṣe ati ọ̀rọ pẹlu.

Inu Jakọbu bajẹ pupọ lati padanu ọmọ rẹ; kò si si ẹnikan ti o le tu u ninu. Sibẹ awọn ọmọ rẹ ko jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn. Eyi yii n fi han bi ọkan eniyan ti le séle to nigba ti o ba kọ̀ lati fi eti si ohùn Ọlọrun.

**AWỌN IBEERE**

1 Njẹ Josẹfu ni abikẹyin?

2 Ki ni ṣe ti o fi jẹ pe oun ni baba rẹ fẹran ju?

3 Ki ni ikorira ati owú ninu ọkàn awọn arakunrin Josẹfu mu wọn ṣe ni ikẹyin?

4 A ta Josẹfu ni ogun owo fadaka, ta ni a tà ni ọgbọ̀n owo fadaka?

5 Ni awọn ọna wo ni igbesi-aye Josẹfu fi jọ ti Jesu?